# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Keedogun: Osu Kerin, Ojo kewa, 2016**

**Akori Oro: E mase jeki awon ota deruba yin -** Apa Kini

**Eko Kika: Filippi 1: 15-28**

## Afihan

Ideru-bani je ohun ti o le mu iberu-bojo wa, O je ohun eru nla ti o le fa ifoya; ni afikun o je isele ti o le sele ti yio mu ki enia diji.
Nipa ti ara ko dara, toripe o le fa eje riru, aisan okan tabi iku. Ni ti emi, enia ko le ri ohunkohun gba lati odo Olorun laisi igboya.

## Irinse awon Okunkun ni Eru nse

Eru je irinse ti awon okunkun saba ma nlo lati mu ipinnu won se, nitori na onigbagbo ti ko ba ni igboya kole bori awon ota ninu ara ati awon ota ninu emi. Iwe (**Orin Dafidi 23: 4)** so wipe "bi mo tile nrin larin afonifoji ojiji iku, emi ki yio beru ibi kan; nitori Iwo wa pelu mi lati tumi ni inu ni igba gbogbo".
Tori idi eyi ohunkohun ti o ba nla koja ninu ara ati ninu emi, mase jeki awon ota deruba o; nitoripe Eleda re yio ran o lowo.

## Olorun ko fun o ni emi eru

Oro Olorun fi idi re mule wipe a ko fun o ni emi iberu ti nso enia di eru tabi fi enia sinu ajaga-ide; sugbon a fun o ni emi isodomo nipa eyi ti awa yio ma fi igboya ke pe Abba Baba **(Romu 8: 15).** E mase gbe emi igboya ti Olorun fun yin sonu, ki awon ota yin ma ba deruba yin.

## Ikilo Jesu

Oro awon Yoruba ni o wipe " mio fe ku kan, kole je oye ile baba re". Jesu Kristi kilo fun wa wipe ki a mase beru awon ti won le pa ara sugbon ti won kole pa emi **(Matteu 10: 28)**. Ese Bibeli yi mu wa ni okan le wipe a ko gbodo beru awon ota wa; sugbon ki a gbe emi igboya wo ni kikun.
Ni igbakugba ti babalawo/onisegun ba fun enia ni oogun/oonde lati lo; won a ki iru eda be nilo wipe o nilo igboya ki oogun yi ba le sise fun.

Ti awon alaigbagbo ba nse eyi toripe won si mo riri igboya, melomelo wa ni awa omo Olorun nilo igboya lati bori iberu awon ota wa; nitori 'aya nini ju oogun lo' ni awon Yoruba wi.

## Awon Aposteli ko fi aye gba iberu

Awon alufa ati sadusi kilo fun awon aposteli ki won mase soro rara, beni ki won mase koni leko ni oruko Jesu; sugbon won gbadura won si bere fun emi igboya lati orun wa. Lehin ikilo yi ni won tun wa jara mo akitiyan won fun itankale Ihinrere **(Ise awon Aposteli 4: 18-31)**.

Awon aposteli koju ija si gbogbo igbiyanju awon ota Ihinrere lati deruba won, Iwo na le se bakan na.

## Dafidi ati Goliati

Apejuwe igboya ninu bibeli ni itan Dafidi ti o lo ba Goliati ti nse omiran jagun. Saulu ati awon enia Israeli ti ndamu, eru nla si ba won nitori ipenija Goliati. Ibasepe Dafidi na beru ni, awon ara Filistini iba ti wipe awon ti segun Israeli, besini ao ba ti so Israeli di eru awon ara Filistini.

Dafidi jade losi ogun pelu kiko orin yi “ bi mo tile kere, mo l'Olorun nla; bimo tile kere o, mo l'Olorun to tobi” nitori o gbagbo wipe ohun ni Olorun Olodumare ti yio ja fun ohun. Dafidi ko imoran oba Saulu wipe ki o ma jade losi ogun, besini o tesiwaju.

Dafidi mu opa re, kanakana ati okuta marun dani losi ogun, nigbati Goliati jade wasi ogun na pelu ihamora , ida re ati oko.

Dafidi pa Goliati toripe ko jeki ota deruba ohun, besini ko jeki giga re, firigbon re, tabi wipe o je jagunjagun lati igba ewe re ba ohun leru. **(1 Samueli 17: 41-51)**.

Iwo na le bori awon isoro ati ota re, niwon igbati o ko ba ti jeki won deruba o sugbon ti o pe won nija pelu emi igboya.

## Awon ese Bibeli lati fi Igboya re mule

A pase fun wa wipe “e se giri ki e si mu aiya yin le, e mase beru, e mase foya awon ota yin: nitoripe Oluwa Olorun re, on li o mba o lo: on ki yio fi o sile, beni ki yio ko o” **(Deuteronomi 31: 6)**.

Ara ninu Oluwa ki tun ni ohun iwuri ti e nilo ki e to gbe emi igboya wo ni isinsinyi, ni iwon igba ti ati ni aridaju lati odo Oluwa ki ota ma ba deruba wa.

So fun ota re pe "Oluwa nbe fun mi, emi ki yio beru; kili enia le se simi "**(Orin Dafidi 118: 6)**. Fi okan re bale, toripe ogunkogun ti a le gbe dide si o lati inu ijoba Satani ni ao parun ao si so iru ijoba be di ahoro nitori re.

Kini idi ti o fi nberu awon ota re, niwon igbati a ti ko nipa tire pe " ko si ohun-ija ti a se si o ti yio le se nkan ......" **(Isaiah 54: 17)**. Ti o ba mo wipe awon ohun-ija ti awon ota se lodi si aiye re ko le pa o lara, kini idi ti iwo ko fi gbe ebun-ofe Oluwa ti nse emi igboya wo?

Ni iwon igbati ati fi Oluwa se agbara emi wa, ko leto ki a tun ma foya awon ota wa tabi ki a jeki won o tun ma da eru bawa mo. Toripe Oluwa ni imole ti nto ipa isise wa si ona igbala emi wa **(Orin Dafidi 27: 1-2)**.

Ni afikun, e jeki a ranti wipe "ohun ija wa ki se ti ara, sugbon o ni agbara ninu Olorun lati wo ibi giga awon ota pale;" **(2 Korinti 10: 4)**. Ni iwon igbati ohun ija tiwa dara ju ohun ija Aiye lo, e jeki a lo ajulo yi lati bori awon ota; ki a masi fi aye sile fun won lati deruba wa.

## Isegun ti Gideoni

Igboya ati okan akin ni o mu Gideoni lo ogorun meta okunrin gegebi itoni Oluwa lati segun egbegberun ainiye awon ara Midiani ati Amaleki. Olorun pase fun Gideoni lati kede ni eti awon enia Israeli wipe; enikeni ti o ba nfoya ti eru ba si nba, ki o pada losi ile.

Egba mokanla si pada ninu awon enia na; awon ti o ku je egba marun. Olorun se idanwo fun awon ti o ku ni ibi odo, ninu won ni o si ti mu ogorun meta pere, lati koju ogun ti egba merindinlogun okunrin nberu lati koju **(Awon Onidajo 7: 1-15)**. Iwo na lo igboya loni, lati gba isegun lori awon isoro ati ota ojo pipe.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Kerindinlogun: Osu Kerin, Ojo Ketadinlogun, 2016**

**Akori Oro: E mase jeki awon ota deruba yin –** Apa Keji

**Eko Kika: Filippi 1: 15-28**

Oluwa ni o da Okunkun Ni iwon igbati o je wipe Oluwa ni o da aiye ati ohun gbogbo ti nbe ninu re, pelu imole ati awon agbara okunkun. Nitori na, awa omo Olorun gbodo le fi owo so aiya wipe okunkun ko le bori wa **(Isaiah 45:7).**

Tori idi yi awa ti a wa ninu Kristi ko gbodo jeki awon ota/okunkun deruba wa tori wipe won ko le bori wa, ayafi ti a ba sako kuro ni ona ododo.

Ti a ba je olufokansin, ti a si je olododo niwaju eleda wa; a ko ni lati beru awon ota sugbon kiki ki a gbe igboya wo bi awon kiniun ni **(Owe 28: 1)**. Mo gbadura wipe Olorun yio fun wa ni emi igboya ti nteri ota ba. Igboya ti ngba ibukun ati ire yio je ipin wa ni ojo oni.

## <u>Sadraki, Mesaki ati Abednego Sadraki</u>

Mesaki ati Abednego ko beru ipinu buburu ti oba Nebukadnessari ni si won besini won ko foya nitori ina ileru. Won lo igboya ati okan akin lati bori ipinu buburu ti oba ni si won, eyiti o mu ki ota ti o fe deruba won beresi ni fi ogo fun oruko ati agbara Olorun Olodumare **(Danieli 3: 5-27).**
E mase jaya nitori awon ota yin besini ki e mase jeki won deruba yin; nitoripe Ekerin ninu ina ileru (Omo Olorun Alaaye) nbe laaye lati dabo bo o ati lati da emi re si. Amo ki se ki o ma lo fi owo ara re fa wahala tabi wa ija awon okunkun lainidi toripe Oluwa wa ni iha tire.

## <u>Ifowosowopo Ibi lori re yio jasi asan</u>

Gbogbo okan ti o parapo nipa ote lati muki iwa-laaye/ise yin o parun ati awon ti won duro lati pa oruko tabi ogun rere yin re kuro ni ibi gbogbo labe orun yi ki yio se aseyori. Awon ota ti ndi panpa lodi nitori yin yio se wahala lori asan **(Orin Dafidi 83: 2-15).** E mase jeki awon ota deruba yin nitori ikorajopo won lati pa oruko yin re ati lati pa iranti iwa-laaye yin run koni wasi imuse.

Siwaju si awon ti o fi ohun sokan ti won si towobo iwe ilodi nitori yin,ni a o da lebi; gbogbo igbiyanju won yio si je otubante.

O ko gbodo beru opolopo enia ti won rogba yi o ka, ni iha gbogbo ni bibeli wi (Orin Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School **2 Dafidi 3: 6**). Nitorina ni igboya ki o si mu aiya le wipe ohunkohun ti o le sele, Iwo ki yio beru tabi jeki awon ota da aiya fo o mo.

## Oba Sennakerubu daiya fo awon ara Jerusalemu

Oba Sennakerubu doti ilu Dafidi ti nse Jerusalemu. O ran awon iranse re si oba Hesekiah ati awon olugbe Jerusalemu; ni igbati o nfi Olorun Olodumare we awon olorun ajoji/kekeke ti awon orile-ede ti o ti segun.

Awon iranse Sennakerubu fi Oluwa Olorun awon omo ogun pelu iranse re oba Hesekiah se yeye, won si ta abuku ba Oluwa lopolopo. Sennakerubu pelu ko iwe lati kegan Oluwa Olorun Israeli besini o so oro odi si eleda gbogbo aiye.
Sugbon oba Hesekiah ati woli Isaiah gba adura si Olorun, o si ran angeli re lati pa gbogbo awon alagbara ogun, awon asaju ati awon balogun ni ibudo oba Assiria. Isele yi mu ki Sennakerubu fi itiju pada si ile ontikarare ni ibiti o gbe ku iku esin ni ile orisa re **(2 Kronika 32: 9-21).**
Oluwa ti o gba oba Heskiah ati awon ara Jerusalemu nbe laaye, Yio gba o sile lowo awon ota/isoro, ni iwon igbati o ko ba ti jeki won deruba o.

Mase jeki awon ota deruba o, toripe ti a ba si o loju emi iwo yio ri wipe awon ogun orun ti a yan ti o; won lagbara besini won poju awon emi ilodi ti won nbe lehin awon ota re lo **(2 Awon oba 6: 15-17).** Mase beru otan, ni iwon igbati Oluwa ti se ileri wipe ohun ki yio ta o nu besini ohun ki yio ko o; ni idi eyi ni awon angeli re yio fi ma pa o mo ti won yio si ma ko o ni ona ti iwo yio rin.

## Awon ileri fun awon onigbagbo

A o so lara awon ere ajemonu onigbagbo eyiti yio fun won ni igbooya ati okan akin, ki awon ota won ma ba deruba won.

- Gbogbo awon onde ni a o gba kuro lowo awon alagbara, besini a o gba ikogun lowo awon eni-eru; Oluwa yio ja fun o, a o si gba awon omo re la.

Olorun yio fi eran ara awon aninilara re bo won,won yio si mu eje awon tikalara won ni amuyo **(Isaiah 49: 25-26)**.

- Olorun nbe fun o, enikeni ti o ba koju ija si o tabi awon ti o pinu lati deruba o yio segbe **(Romu 8: 31)**.
- Awon ota re yio teriba fun o, won yio si la ekuru ese re; ti o ba gboran ti o si te siwaju lati tele ase Oluwa **(Orin Dafidi 72: 9).**
- Gbogbo awon ota re ti nbinu si o ni oju yio ti, won yio si damu; won o dabi asan, awon ti nba o ja yio si segbe. Awon ti nba o jagun yio si dabi asan, iwo yio wa Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School 3 won, iwo ki yio si ri won mo; toripe a o pa iranti won re kuro labe orun. Oluwa yio si di owo otun re mu, yio si wi fun o pe ma beru, emi yio ran o lowo **(Isaiah 41: 11-13).**
- Ma ke pe oruko Oluwa nitori wipe ile-iso agbara ni, eyiti awon olododo ma nsa wo inu re fun abo lowo ota/isoro **(Owe 18: 10)**.
- Awon ota yio ba o ja, sugbon won ki o le bori re;nitori emi wa pelu re, ni Oluwa wi, lati gba o **(Jeremiah 1: 19).**

Ni akotan lati oni lo, Olorun yio beresi fi ifoya re ati eru re sara gbogbo awon ota re; Ni igbakugba ti won ba gburo re, won yio wariri besini won yio se ipaiya nitori re **(Deuteronomi 2: 25).**

Bere lati oni, owo ti yipada, awon ota ni yio ma beru re; ni gbogbo igba ti won ba gburo re; won yio wariri pelu iberu-bojo. Ni iwon igbati o ko bati ya kuro ninu ase Oluwa tabi se aigboran si awon ase re.